IBINU KO DA NKAN, SURU NI BABA IWA



AWOGBA Omode fun Giri, Eyi, Hiba-ehin, Orere.
Ra Tir Ni Ile Egbogi
— ISE —
Olodumare Okebola, Ibadan.
116, Great Bridge St., LAGOS

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

TO CLEAR
Gents Suede Court Shoe
Brown, Black & Grey
Before 50/- Now 42/6
Obtainable at:
A. B. AKINYEMI
10A Moloney Bridge St
LAGOS.

VOL. No. VIII 474. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, JUNE 30, 1956. KOBO MEJI (2d.)

# Ibinu Ko Da Nkan. Suru Ni Baba Iwa.

Odomokunrin kan nfe omobinrin wundia kan ni Ode Ojo, sugbon awon obi omo wundia na ko fe ki omo won fe omokunrin na, nitoripe enia buruku ni Onsegun si ni. Enia pipa ko jamo ohun kan l'oju re.

Alarina so wipe, nje ti ore on ba fi iru iwa ti e wi yi sile nko, e o ha fi omo na fun lati fe ndan? Nwon si dahun pe, bi o ba ti le wa bu Orisa Ogun niwaju awon pe on ko ni hu iru iwa bawonni mo, lau-lafia.

Lojo keji okunrin na ati alarina ko ese si bata, o dile iyawo. Nigbati nwon ti gba awon mejeji l'alejo tan, nwon wi fun pe, nwon so fun wa pe, Ologun ni o ati wipe ko si eniti iwo ko le pa.

Kini omokunrin na gbo eyi si, nse ni agbari re gbo'na, o dide lesekanna o wipe Ha! tani so be, e-mi, e-mi, enito wi be, ko ni sere. Nigbana ni won wa koju si Alarina, nwon nje won si nkorin bayi wipe:-

Eyi mo wi re,
Oro apara dija.
Lesi mo ba ja nile nyin
Ki e to gb'ariwo!

Beni awon obi iyawo ko ti nwon ko fi omo won fun niyawo mo.

Okunrin na wa mu ejo re lo siwaju Bale Akintayo, o ko ejo, o ro o, awon obi wipe omo wa taku lati fe Ologun, awa si ti gbo irohin lorisirisi nipa okunrin yi pe Ologun nise. A si ma sepe fun enia, eyi nidi re ti awa ko fi fun ni omo wa. Nse ni agbari okunrin na tun gbo'na, o wipe enito so be fun nyin ko ni sere!

Bale dahun pe a ha le penis l'ole ki o ma gbomo eran jo?.

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited.

Ile ifi Owo pamosi yi
Nfi ona owo han eni
Bi o ba fe je onisowo pataki ao
ran o lowo nipa wipe ao to o
si Ona ti o dara, ao la oju re
si Ona owo lati ilu Okere wa
Bakan a si ni a tun nse iranlowo fun
gbogbo oja ile wa ti anta si agbaiye.

ILE ISE WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWON ASOJU WA NILU OBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

# Oba Titun Je Ni Ijebu-Igbo

Oba Daniel Adetayo Sami gbade gegebi Orimolu Ijebu-Igbo dipo oba Joel Adeboye I. to ku sinu oko ofurufu l'ojo kokanlelogun osu kesan odun to koja.



OBA DANIEL ADETAYO SAMI
Orimolusi Ijebu Igbo

Ojogbon iwe ni Oba yi nitori Ile Eko Giga ti awon Oluko ni Oyo (St. Andrew's College) lo ti pari eko re. Ose ise oluko ni Ile-Eko ti C. M. S. Okebola, Ibadan, lehin eyi lo se akowe ni bi ise oko oju irin (Railway Accounts Department) ki o to wa di omnira ara re gegebi onisowo nilu Eko,

Oba yi je akowe Igbimo ti nbojuto Ile Eko Giga Molusi, Ijebu-Igbo (Ijebu-Igbo Patriotic Society) ati Olu akowe ti gbogbo Egbe Obinrin Ijebu-Igbo. Ninu iwa ati ise re, o ti wulo pupo fun itesiwaju ilu Ijebu-Igbo, a si ni ifokanbale pe nisisiyi gan lo wa bo s'enu ise na ti Oluwa yan sii.

O je ohun idunnu pe Gomina Ijoba Ipinle Iwo-Orun ti fi ase si ifijoba re, awon Igbimo Ijebu-Igbo ti fi ife, aniyan ati isowopo tun ilu se han nipa yiyan Oba yi ni Olori ati Alaga Igbimo Ilu Ijebu-Igbo.

Aye de si Ijebu Igbo, gbogbo ara ilu lomode-lagba ninu oso to daihiri ni won pese sibi igbade na.

Orisirisi aso, ilu ati ijo l'ongbara won, irohin ko to afojuba, ogunlogo ore, ojulumo, asoju awon Oba ile Yoruba ati awon asoju Igbimo Ijoba Ipinle Iwo-Orun wa sibe pelu. A o ma fun yin ni irohin ki kun ninu iwe wa ti ose ti mbo.

Lati ojo ketadinlogbon osu kerin odun yi ni Oba yi ti bere ato. Eto ile'te gba ijo meje, lehin eyi lo lo si Odo ni Odo-Aiyeku nibi ti gbogbo awon ara ilu ti wa nfi ilu ati ijo ki i l'ojojumo titi wa di ogunjo osu kefa odun yi ti o fi fi tijo-tayo pada si ilu fun igbade. Ninu awon to wa bewo ni Odo Aiyeku ni Olola Obafemi Awolowo, Oloye S. L. Akintola, Ogbeni Ola Ijebu-Ode Oloye T. A. Odutola, Bobasuwa Ijebu-Ode, Oloye E. O. Okunowo ati gbogbo awon egbegbe ati ogba-ogba Ijebu-Igbo.

Adura wa ni pe ki Olorun ko fun Oba yi ni ogbon, oye, imo, suru ati emi gigun ti yio fi gbe ise na yori ju ti asiwaju re (eniti ike ati ige Oluwa yio ma ba ni aludo orun) lo.

Ki Ade pe l'ori, ki bata pe l'ese Oba, a tu u, a Ba o, Kabiyesi:

# Oni Pa Enia Je

KUMBA— Agbo wipe Oni (Crocodile) fo mo oko kekere ti obinrin kan nwa koja l'ori odo Mungo nilu Kamaru, o si pa obinrin na je.

Obinrin na je iyawo Ogbeni Ewene ti ise olori abule Mundame, ajeku ara re ni nwon ri gbe.

## Adesegun D'OLOGBE

Gbọ́kọ́ ri gbọ iku Oluko F. B. Adeṣegun ẹni ti gbogbo eniyan mọ ni Oloyinbo Gesi rafanda, Alayikorovi ede, ati akọwe fun awọn awọn Oluko ati ọkan ninu awọn Oṣelu.

Ologbe yi je ọkan ninu awọn oluko ilewe St. Paul Breadfruit nilu Ẹko, o ku file aiye sile nigbati o di ẹni ọdun mejidin-ladọta.

Aisan di kekere kan ni a gbọ wipe o ṣe, o si di ohun ti nwọn ni lati gbe lọ sile Alaisan, lati ile re ni No. 8, Ẹlẹgbata Street, ko si rẹ pupọ lehin ti o de ile Alaisan ki o to wọ isalu ọrun lọ, aremabọ.

Ologbe yi ku, o fi iya rẹ silẹ l'aiye, o fi iyawo rẹ, ọmọ meji ọkunrin ati obinrin kan. Ninu ile isin St. Pauls Breadfruit niwọn gbe ṣe isin ikẹhin fun lọjọ Thursday 28th oṣu June 1956.

Adeṣegun, Oloyinbo rafanda, oṣelu pataki, awọn ẹgbẹ "Brain Trust" ko ni gbagbe rẹ. Bi o ba de'le, ki o ki'le, bi o ba de ọna, ki o bere ọna, atetede'le ki o ma ki baba rẹ.

Maṣe jẹ ọkun,
Maṣe je ekolo,
Ohun ti nwọn ba nje lajule ọrun ni ki o ma ba wọn je.
Sunre, sunre, Sunre.
Baba, lọwọ rẹ l'a fi ẹmi rẹ le.

EMIR TI ILU KANO



Aworan inu iwe wa yi niti Ọba ilu Kano, ilẹ awọn ọmọ Alahusa, ti o lọ fun itọju Oju rẹ ninu ile itọju alaisan oju ti nwọn npe ni "Moorfields Eye Hospital" nilu nla London.

Nigbati Emir Kano pẹlu ọmọ rẹ Alhaji Ado Sanusi, ati ọmọ-ọmọ rẹ Baba, fẹ w'ọkọ Ofurufu ni'budo ọkọ nilu London lati pada silu rẹ. Ọmọ-ọmọ Ọba Kano na ni ẹ awo ti o di ika-ọwọ Ọlọla Alan Lennox-Boyd mu pẹlu ẹrin idunnu yen


# BENI O LE RA EYITI ODARA JULỌ

NITORIPE

Ohun ti o Dara Julo Loni Emi Gigun

O wa ni Awon Ile Itaja nla ti o wa ni to si yin.





o si tun wa ni Ile Itaja Singer
TI O SUN MỌ Ọ
94, Broad St, Lagos.
24, Jebba St. West,
Ebute Metta.

ATI PE

## Machine Aronso ti o Dara Julo

Ni Gbogbo Agbaiye Ni

## SINGER

E kowe si wa kia-kia Fun Iwe Oja Wa.

## Tani le dahun ibere nwonyi

OLOTU. Jọwọ gba mi laye lati fi ibere nwọnyi siwaju awọn ọkawe rẹ, ki awọn to ba lọgbọn ninu ti o ba si ni imọ laiya ki o fun mi lesi rẹ. Ibere na niwọnyi. Ẹniti o ba dahun gbogbo rẹ yio gba-ẹbun.

Ẹniti o ba dahun ibere yi ki o fi ranṣẹ si Ọgbeni Ọladayọ Ogunkọla 23, Johnson Street, Lagos, Nigeria.

1. Mẹrin ni orukọ mi Ọrọ to kọkọ bẹrẹ ni D.. .. .. kini awọn ọrọ yoku?
2. Kini ko si ni abule Eko?
3. Bank wo lo dara ni Eko?

## Egbe Afenifere Fe Yo Ayo Isegun L'oke Oknn

Awọn ẹgbẹ Afẹnifẹre ti o mbẹ ni oke Okun, nṣe ipalẹmọ lati yọ ayọ iṣẹgun ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni lori ẹgbẹ N.C.N.C.

Tabi iwọ ko gbọ bi awọn ẹgbẹ Afẹnifẹre ti nkọrin lọjọ Iṣẹgun ni Eko? Nwọn nkọ orin na bayi wipe "Ẹgbẹ olowo lẹgbẹ Awolọwọ, mọto ni yio pakukọ ṣu-ṣu.

Agbọ wipe awọn ara Oke okun nreti ki nwọn pari idibo ilẹ Aganyin tan ki nwọn to yọ ayọ na, a si gbọ wipe ni ilu Kumasi ni nwọn o fi ibujoko ọjọ ayọ na si. Lọjọ 17th oṣu July 1956 ni a gbọ wipe nwọn fi ọjọ na si.

O yẹ ki gbogbo awọn ọmọ ti a bi silẹ karọ, o jire lọwọ sinu ọjọ ayọ na, nitoripe ti wa to bẹ, o si jubẹ lọ. Bi o ba jẹ wipe awọn Ajeji lo tun wa paṣẹ fun wa nkọ? Kamari.

Ṣugbọn bi o ba kan ọran ti Kiniun yio fi ṣe akapo fun Ẹkun, ọlọdẹ ni yio fi ọwọ mu ọdẹ rẹ.

## Bami Rerin Die

Nigba lailai ti iya Ọba ma nlọ na ọja Akẹsan ni Ọyọ, Iya Ọba pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ lọ jijọ na ọja yi l'ọjọ kan.

Nigbati nwọn nnaja lọ, obinrin kan ti ko mọ Iya ọba ri, yaju si i, ọrọ na si bi Iya Ọba ninu tobẹ ti o fi wipe :-

Iwọ obinrin yi, tani iwọ tilẹ nfi mi pe emi Iya Ẹbọ?

Gbogbo enia ku sẹrin nigbati nwọn gbọ, eyi mu ki inu tunbọ bi Iya Ọba O tun yiju pada si awọn ẹmẹwa rẹ, wipe, awọn tani nsọrọ ti ẹniyin ti nrẹrin tabi ẹ ko ri ti o nyaju si emi odidi Iya Ẹbọ?

Gbogbo awọn enia to gbọrọ yi tunbọ bu sẹrin, obinrin kan lo jẹki Iya Ọba fura nigbati o ntun ọrọ na pe wipe, "Iwo ni wọnawọnyi ẹwẹ, Iya Ẹbọ tabi kinla!

Nigbayi ni Iya Ọba to wa fura pe Ọrọ gbe on sọ. Nṣe ni on na papa tun bu sẹrin.

Awọn Ẹbi Ogbe Alayọ sọ wipe

OVALTINE

wa fun ilera ati inudidun!



AWỌN ẸBI OGBE

ti nwọn gba ẹbun ti apapọ Ẹgbẹ kede sinu "Sunday Times" fun idije awọn ẹniti ẹbi rẹ ba ni inudidun ju ṣe awọn eto inudidun kan ti ko mu inira dani. Jẹ onjẹ atata, sun fọnfọn, ki o ma si ṣe wahala! Bẹni awọn Ẹbi Ogbe nmu OVALTINE lẹmeji lojumọ, larọ ati lalẹ. OVALTINE nfi gbogbo awọn ohun ti o le fun ni ni alafia ati ilera kun onjẹ ti o ba njẹ, o nfun ara ni okun ati idẹra ati igbadun orun. Wa si ji dide pẹlu isọdọtun agbara ati alafia. Ṣe afarawe awọn ẹbi Ogbe, ma a mu OVALTINE nitori ilera ati inudidun.

Gbigbona tabi tutu




OVALTINE

–ko si ohun ti o dara to!

OWA 18/7

# ELETI ỌFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - OFE LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23379

VOL. VIII. NO. 474. LAGOS, SATURDAY JUNE 30, 1956.


## Gedegbe L'eko Wa Abo Re O!

"Igba ira l'a mbura, aki i fu Sango rigba ojo", Oṣe bi owe, Irohin kan ti a gbọ l'ọmuwa p'owe eke yi fun ẹnyin ọkawe wa, nitoripe asiko ti irohin na de eti'gbọ wa yi bọsi rẹmurẹmu bi-ẹni nf'adin mu'kọ.

A gbọ wipe Ijọba Ibile Ọyọ fi ala? a obinrin kan ranṣẹ si ilu Eko yi wipe ki ijọba ilu Eko ṣe itọju rẹ nitoripe ọmọ Eko ni alagba iya na rṣe.

KILO FA SABABI.

Ohun ti a gbọ wipe o fa sababi wiwa iya na wa si Eko ni wipe iya na ti lọ fi ilu Ọyọ ṣe atipo rẹ tla i igba ... ṣugbọn nigbati ọjọ ore oke ale fun u ... se 'un'rere mọ, ti ati ẹ ati ... timu ... ki ko si ... ni'lu Ọyọ ... nil ti t'evọ ba, ni Ijoba Ibile Ọyọ ... si ... ilu Eko, nitoripe "GEDEGBE" 'Ek ... aram ... ilẹ Yoruba ti iṣe iran rẹ.

... eria wa, nigba'i a nki'gbe fun ... ko rapo mọ ilẹ Yoruba yoku, ki afi ... ri ... ọmọ al nde, wipe Gedegbe l'Eko ... eredi a ọ rẹ l'a nri yi o.

... mọ ilẹ Yoruba ni, iru eyi ki ba ... i ṣe rara. Nito ina ẹiẹ i a pa'nupọ sọ wipe gbogbo wa ... fẹ ki a p ... wa Eko pọmọ ilu Oke, ilẹ Yoruba, ki ale ri igbadun ati alafia ara wa.

LỌWỌ IKU OJIJI, OLUWA RERE GBAWA

Aṣe ṣe wa gidi idi nigbati a gbọ irohin Ọkọ Ofurufu ti jamba ṣe nilu Kano, ti ọpọlọpọ ẹni awọn enia d'oku ọrun airotẹlẹ, gẹgẹbi ati tẹ agbọju'gbanu irohin iṣẹlẹ buburu na sapakan iwe Irohin wa ọsẹ yi.

A fi wosika wa yi ba awọn ẹbi, ọrẹ ati ojulumọ awọn enia ti jamba na ṣe kedun gidigidi, ki Oluwa ṣọwa lọwọ ewu Moto, ti Reluwe ati ti Ọkọ Ofurufu, ki o si gbe awọn oku na sinu afẹfẹ rere, ki a ma tun ri irufẹ eyi mọ. amin, aṣẹ, bẹni k'ori.

## Ako Fe Eko Ni Gedegbe

Nipa ede koyede to bẹ silẹ ni ilu Eko larin Ọba Eko ati ẹgbẹ Afẹnifẹre. Eyiti a gbọ ni wipe Ọba Eko ṣafẹ ki ilu Eko, ati Epẹ ati ilu Badagry wa gedegbe lọtọ fun rarẹ, ki Eko ni Igbimọ Assembly tirẹ, ki o ni Prime Minister ki o si ni ijọba tirẹ, bi o ba jẹ wipe awọn oyinbo kọ lati pa ilu Eko pọ mọ ilẹ Yoruba yoku ni u igbimọ ti nwọn nlọ ṣe nilu Ọba.

Ọba Eko pe ipade gbogbo awọn ijoye ilu Eko jọ ati awọn ọmọba, ati awọn ijimi eria sinu Iga Idunganran, nigbati ẹsẹ awo pe oba wa na ọrọ yi silẹ niwaju wọn. Alufa Lemọmu Aṣafa lo kọkọ fesi wipe, Yoruba lo ni ilu Eko, Yoruba lo tẹ ẹ do ko si tabi-tabi wipe ki a paapọ, tabi ki a mapa apọ, mọ ilẹ Yoruba yoku. Awọn ijoye nwọnyi fi ara mọ ọrọ ti Lemọmu Aṣafa sọ Oloye Olumẹgbọn Oniru, Onilẹgbalẹ, ati Kosọkọ.

Ọrọ yi jẹ ibinu ati ibanujẹ fun gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti o mbẹ nilu Eko lọkunrin, ati lobinrin ti o mbẹ nilu Eko nigbati nwọn gbọ wipe ọba nfẹ lodi si ete ati e o ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Awọn ijoye Eko ati awọn ọmọ ọba so wipe nigbati nwọn ba lọ silu Ọba lati sọro ilu bi nwọn ba gbe ọrọ ilu Eko jade lati pa a pọ mọ ilẹ Yoruba bi ko ba ṣeṣe, ki a fi gbogbo ọrọ na le ẹgbẹ Afẹnifẹre lọwọ. Nitoripe iru anfani ti awọn nje loni, ẹgbẹ na lo gbe won de ibẹ. Ọba Eko kan ko l'ẹnu nin u ọrọ ilu ri, ẹgbẹ yi lo gbe wọn debẹ, Ijoye kan ko le sọro larin ilu ki o ta ri, ẹgbẹ yi lo gbe wọn debẹ.

Lẹhin na ni a gbọ wipe, Ọba sọ fun wọn pe ohun ti on nfẹ ki o ye wọn niyi, ilu Eko ko le wa bayi titi, ohun ti on gba lero niyi, wipe, aibamọ nigba ti nwọn ba lọ silu ọba lati sọrọ ilẹ wa, bi awọn oyinbo ba kọ lati pa ilu Eko pọ mọ ilẹ Yoruba yoku ki a fi Eko si aye ti o ti wa ri, ki a pe ijọba tiwa ni Lagos State, ki a si ni ijọba ti Eko lọtọ funra rẹ gẹgẹbi awọn agbegbe yoku ti ni.

Ọrọ yi koiti fi idi ti sibikan, o ṣi nja ranyin nilẹ.

## Ona Moto Ti De Ilu Ojo

O ti le lọdun mẹjọ ti awọn Awori ti nlọ ibosi fun ijọba wipe awọn nfẹ ki ijọba la oju ọna mọto fun wọn lati Ajegunlẹ Apapa titi lọ de ọja Ọjọ.

Nigbati nwọn nreti wipe ki ijọba dahun si ibere wọn ti nwọn ko si dahun, ni awọn enia na ba dide funra wọn ti nwọn si ṣan'gbo lati Ọjọ titi de Apapa.

Ọwọ ẹni ko sa ntan nijẹ, nigbati ijọba roye pe, nitotọ ni awọn enia na nfẹ ọna mọto, nwọn ndide nwọn ṣe kereni sori odo Ajọto, i abule Ọṣun ati ti Apapa.

Ṣugbọn nisisiyi Moto ti nrin lati Eko titi lọ de Ọja Ọjọ, nwọn si ngba owo ero Moto lati Apapa de Ọjọ ni nain (9d).

Ijọba ti ṣeleri pe nwọn o bẹrẹ si tẹ ọna na laipẹ.





Bi o ba ru eru to wuwo fi egbogi ajebidan pa gbogbo ibiti o dun o

IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ ewa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

ỌMORELA BABY MIXTURE

(SILE MEJI ABO 2½d. FUN IGO KAN)

O wa lọdọ :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS

## Aki Igbo Buruku L'enu Abore

Nigba lailai, nilu kan l'ọna ilẹ Oke, Egungun kon wa ti a npe ni "Pajẹ-Polobi", bi Egungun na yio ba jade, gbogbo enia ti mọ wipe iṣe Ajẹ pipajẹ ni iṣẹ rẹ, bi o ba ti jade, on lọ bẹ obinrin Ajẹ kan lori niyen.

Nigbati Egungun yi ti npa gbogbo obinrin to ba ni Ajẹ nilu, ko si ibẹru ṣugbọn Iya Ọba ilu na papa ni Ajẹ, awọn ara ilu wa bẹrẹ si sọ ọrọ na nikọkọ nibaba titi, wọn sọ deti Egungun Pajẹ yi, Egungun na wa pinnu wipe on yio paa jẹ.

Egungun, na ransẹ si gbogbo awọn ọjẹ Elegungun awọn bi Alagbaa, Iya Agan ati gbogbo awọn to j'oye ninu Ọjẹ. nigbati ẹsẹ wọn pe ni o fi ọrọ yi siwaju wọn, o bi lere bi bẹni tabi bẹkọ? wọn si da lohun ni ọrọ kan wipe bẹni. O si sọ un wọn wipe ni ọjọ mẹtadinlogun oni ni on yio jade, bi on ba jade ile Ọba ti iya Ọba ba joko on yio k'igbe wipe "Iya Ọba laa o"! ki ẹnyin Ọjẹ si da mi lohun wipe "jẹẹ o", gbogbo wọn si wipe kai! Owi're e fọ're.

Nigbati ọjọ pe, oju t'pe, ẹsẹ ti pe si afin Ọba Iya ọba papaa gunwa o joko. Ọba na wa nijoko ati awọn Ijoye.

Egungun Pajẹ Polobi bo si ta. o njo yida agbo, nigbati o dewaju Iya Ọba, o kigbe pe Iya oba la-a-a-a o! Nigbati oba gbọ bayi, odide kian lati gbọ ohun ti nwọn nfẹ wi, ibẹru Ọba ko jẹki awọn Ọjẹ le dahun, bẹni egungun na jo kọja lọ.

O tun pada nigba keji, nigbati o dewaju iya ọba, o wi bakanna, ko si ẹniti o le dahun bẹni nigba kẹta pẹlu. Nigbayi ni Egungun na wa darin bayi pe Iya ọba lalubarika ni mo ma wi o. Awọn Onilu ju ilu si, ati ọba ati ijoye ati iya ọba na pẹlu bẹrẹ si jo.

Eyi na lo di owe titi di oni yi wipe "Enu rẹ ni ki nwọn ti gbọ pe Iya oba laje".

Aki igbọ buruku l'ẹnu Aborẹ o.

## Idajo Kotu Lori Apania

IBADAN—Ẹjọ Raji Ajani ọmọ ọlọdun marundinlogoji l'ọjọ ori rẹ ti o nṣiṣẹ ata Koko ati Ekurọ nilu Ẹdẹ, ti nwọn fi sun ẹsun apania lori iku baba rẹ, arabinrin rẹ ati arakunrin rẹ, ti gbogbo awọn to pa na jẹenia mẹrin ni ọjọ kọkanla oṣu November ọdun tokọja

Lati nkan bi oṣu meje s'ẹhin ni nwọn ti wa l'ẹnu ẹjọ yi ki Kotu to ṣe idajọ. Ninu idajọ Adajọ Dr Hedges niba ṣoki, o sọwipe irufẹ ọrọ ẹjọ to dikoko bayi, bi iru eyiti a fi ọdanran yi sun, wipe baba rẹ mbẹ ninu awọn enia ti o pa ijọba nilati fihan gedegbe wipe ọdanran na lo ṣe iṣe buburu na; eyi si ni ijọba ti se ni aṣeyanju ninu ẹjọ yi.

Nitorina, Ajani, yio ku ikn iyẹgi-mọlẹsẹ-pa fun pipa to pa Salami Ayinde, arabinrin rẹ, Layide, arakunrin rẹ, Rufai, ati arabinrin rẹ Aina.

Adajọ fun ni ọjọ mẹdogun lati fi ṣe eto ẹjọ kotẹmilọrun bi o ba fẹ.

## Agbako omo Jaguda

Obinrin kan ti o ṣẹṣẹ de lati oke okun wa sile wa wo awọn enia rẹ lọ Banki ni Ẹhingbẹti lọ gba owo. Bi ti o gba owo na tan o di i sinu apamọ, o si npada bọ wa sile.

Ṣamọ-ṣamọ, awọn ọmọ Jaguda ti ri i, nwọn si tele lehin. Bi obinrin na ti nfẹ gba kọrọ kan jade, nwọn ọmọ Agbewiri ni pe e, o si duro lati gbọ ohun ti nwọn fẹ wi. Ọkan ninu wọn mba soro gẹgẹbi eniti o ti mọ ọ ri, ẹnikeji fi ata lilọ sọwọ, o si ṣan mọ l'oju, ẹnikẹta ja owo ọwọ rẹ gba nwọn si salọ bamubamu.

Obinrin na lọbes gbe-e, o nwipe, Ye, ye, ye, oju mi o, nwọn ṣan ata mọ mi loju loju ye, ye, ye, Owo mi o, nwọn gbe owo mi lọ. Obinrin yi kotete ri alanu. nitori bi o ti nkegbe oju, bẹni o nkigbe owo, nipa bayi nwọn rope were ni, oṣu ṣẹṣẹ le ni.

Ki obinrin yi to ri alanu gbogbo oju rẹ lo ti wu kubọkubọ, o si nta a, ọlọpa kan ti o nkọja lọ lo ṣe anu rẹ ti o mu lọ sile alaisan, ṣugbọn awọn ọmọ Jaguda gbe owo re lọ gbe. Lọwọ ole, ipania, ati ọmọ Jaguda, Oluwa rere gba wa.

## I. Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe l'ose'ose


Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS



*Read this list of popular titles*

JZ. 5825-Ey di Hwsa / Asew Dsai- J. Squire Addo.

" 5831-Onyipa Wo Dee A Oye/Wenyina Nnhu Adze - Sampson's (Band).

" 5928-Idajo Aiye / O pe - Iwajowa Native Air Party.

" 5960-Sabo/Lamulana) Tauridi Sule &
" 5961-Eko Ile/O-K-K) His (Apala) Band.

" 5962-Edumare Sanu Wa / Coastal Blues) Rainbow Dandy

JZ. 5963-St Peter's Tragedy/(B... M Lefe) Ord...

" 5973-Baca Ware/Owei Youths-Ijaw Youths Orchestra.

" 5974-Israel/Olokun ) Kasumu
" 5975-Asiwaju/Arobieke) Adio & His (Apala) Band

" 5980-Adebeye II/ ) - Dauda Yinusa Ologbon Aiye) & His
" 5981-Adake Dajo/ ) (Apala) Aromisa ) Band.

" 5987-Awigbo/Lawal Ayinde
" 5988-Adura Owuro/ ) Fakaro & Olowu of Owu ) His (Juju) Band.

*Sold by all the best stores*

"HIS MASTER'S VOICE" *Yellow Label* RECORDS

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

## Igbehin Re Ju

Lati Owọ
AKINTUNDE ṢOWUNMI

Eyi li ẹkunrẹrẹ arofọ ti Ọgbẹni Akintunde Ṣowunmi sọ lori ẹrọ asọrọ-magbesi ni ọjọ Ru, ọjọ kẹtala oṣu June 1956

A tẹ arofọ na, nitoriti awa gbagbọ wipe, o kun fun ẹkọ ọgbọn ati iṣiri fun gbogbo enia, a si rope awọn ọkawe wa yio lara bale ka a. E fi ohun ede Ẹgba ka a.

Awọn yi wipe aiye dun, ko si wi rara,
Awọn yi wipe aiye koro, ko sọ isọkuso
Igba yi aiye yi si kaluku ṣe o nwi kiri,
Ohun ti nrekọja nigba aiye, ko gbọdọ mu wa ṣiwahu
O ṣa dajo pe, igba kan ko lo ile aiye gbo.
Avida re olotu igbesi wa.
Adun ati koro aiye ki ṣe l'ẹnikan
Igba rẹ, igba mi,
Tibitire jẹka rora lo gba;
Igba mi, igba rẹ,
E jẹka lo gba si rere
Igba a lo wọn o, ara mi,
Awọn to ba lo igba ju bo ti ye;
Igba: igba: igba igba: igba;
Bigba ba so igba, a ma fi ṣeru, a ma fi mumi,
Bigba ba so igba, a ma fi dabẹ se
Bigba ba so igba, a ma fi goke iṣoro,
Ṣugbọn igbi igba bo so igba ni di ẹni, ọran ko dẹ wọ;
k'Edumare jẹki igba yi so gba yi gbo fun wa ri da'kọ mu,
Ko jẹki igba so igba yi dun fun wa sebẹ;
Ko jọwọ jẹki igba so igba yi ko ni tete ja fun wa ri goke iṣore,
Ko ma jẹki igba so gba nidi ẹni!
K'a ma bajẹ k'a to dara l'aiye ọmọ enia
Igba so gba nidi ọrẹ kan o ke tan tan,
O kọwe ibanujẹ rẹ ranṣẹ sọdọ mi,
Mo kawe na tan, inu ko dun,
Iwun bami n'nu jẹ ninu rẹ ki lṣe inira to ba jagun,
Bi koṣe a mọ umọ aiye ọmọ enia.
Ọrẹ na ṣe'regbe titi, o sọ wahala rẹ dede, o bere imọran.
Hun: Imọra ;
Ọrẹ ko mọ pe, o kari aiye, aṣọ iṣoro,
B'o ti wa lara akọ, l'o wa lara abo,
Tọmọde - tagba re r'a'belebu aiye Akamara;
Ọrẹ sọ pe, on dupe fun arofọ, "aiye l'ọja"
O sọ pe ṣugbọn o dabi ẹnipe on npofo,
Bẹ n ko gb'ẹbọra wa n'ọja;
Aiye l'ọj , ọja ntu lọ,
Sibẹ on ko ri k n ṣe kan.

## Awon kokoro to npa ohun ogbin

Ninu irohin oṣu mẹfa-mẹfa ti awọn awujọ ẹgbẹ Agbẹ ma nṣe, awọn mẹnu kan awọn kokoro to mba awọn ohun ogbin jẹ nilẹ Nigeria. ọgbẹni W.J. Hall lo sọrọ na.

Oṣọ wipe awọn kokoro Abuta Eṣu, Kori-kori ati labalaba ba ọpọlọpọ awọn ohun ọgbin jẹ bi Ọsan, Owu, Gbaguda, Koko ati Obi, awọn ohun ọgbin bi Agbado, Iero, Ọka-baba, ti awọn kokoro na bajẹ ni lọlọ yi. ko ṣe ni, Bakanna pẹlu ni Oke-Ọya gbogbo Irẹsi ti nwọn gbin ni awọn kokoro Aparipa bajẹ ati Dawa tabi Iero.

Ijọba ti gbe awọn enia kan dide, olukuluku wọn pẹlu ẹrọ afọn-ogun lati ma fun omi egbogi sara awọn ohun ọgbin na, ni apa agbegbe Iwọ Orun ile Nigeria.

## Idahun si ibere Alhadji Siaka

Olotu,

Gba mi laye lati dahun si ibere Alhadji Isiaka ti ọjọ 21st oṣu April 1956 ti o jade ninu iwe Eleti-Ọfẹ ni u eyiti o bere wipe hawo ri enia fi le gbe ẹru mẹta ni Agbado, Kọlọkọlọ ati Adiẹ. Gẹgẹbi ọgbọn temi ni wipe yio kọkọ mu Kọlọkọlọ Agbado lọ na ki o to wa gbe adiẹ.

Emi ni

Yesufu A. Adeyẹmi

ara Ivory Coast.

**Kere o!**

A ti ni orisirisi ogun Germany to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos

## Jamba se oko ofurufu kan ni Kano

Agbọ irohin wipe jamba ṣe ọkọ ofurufu ti (B.O. A.C.Plane) kan ti o ṣi kuro nilu Eko, o nlọ silu London Nigbati ọkọ na ṣi kuro nilu Kano ni wọn dede agogo mẹfa-abọ aṣalẹ ni a gbọ wipe enia mẹrindilogbọn lo di oku ọrun, enia mejidinlogun ko ku, ṣugbọn enia mẹta l'o farapa pupọ.

Ọkọ na ti rin bi ibusọ kan ki o to wa kọlu igi to fa sababi jamba yi. Agbọ pe ero pọ ninu ọkọ ofurufu na, awọn ọmọde kekeke mbẹ ninu wọn.

Njẹ lọwọ ewu Moto, ti Reluwe, ati Ọkọ ofurufu Oluwa rere gba wa.

## Isimi Odun Ileya

Ijoba ti ṣe ikede yi pe a o kirun ọdun Ileya ni ọjọ kejidinlogun oṣu July, 1956, l'ọjọ Alaruba.

Nitorina, isimi kuro lẹnu iṣẹ yio wa l'ọjọ ọdun ati ọjọ iharan, eyi ni ọjọ kejidinlogun ati ọkokandinlogun oṣu July, 1956.

Nigbati o ba si di ni ọjọ kẹtadinlogun oṣu October, ni a o ṣe ọjọ Ibi Anọbi Mohamad (Maolud-un Nọbiyi) Isimi yio si wa l'ọjọ na pẹlu.

**Now Available**

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS, DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just Write, Call Or
Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
AND
NEW COURT ROAD,
IBADAN




Aniyan fun ilera ati idunnu awon enia lo fa eto tito ilu ni Ipinle Iwọ-orun.

Apẹrẹ kan pataki nipa aniyan na li eto ilu Ajowa ti a ṣẹṣẹ tẹdo lagbegbe Ọwọ. Gẹgẹbi abajade akitiyan Ile-iṣẹ ti nmojuto oran ile ati tito ilu ni Ipinlẹ Iwọ-orun, pẹlu iṣọwọpọ awọn enia, ẹdẹgbafa enia nino abule mokanla lo gbarajọ lati ma jumọgbe ninu ilu titun na ti a tẹdo lọna ilaju ode oni.

Ira eto bẹ nlọ lọwọlọwọ ni Ifẹ, Abẹokuta, Sapẹlẹ ati Ikẹja.

Ile-iṣẹ Alarina Ijoba Ipinle Iwọ-orun lo ṣe ikede yi.

# Alaye nipa awon etutu ile wa.

Nigbati awọn Ba'alawo ... ki a ... alaisan ... fi rṣe ... ati Aruk... ṣ-gu ... ri ... ko ... fi iṣ etu... Eiyẹl ... ri ocidi ... Fun ... Of ile ati ... eyin Adie. Fun e'ọ ... lile, ... Wah ... Ebọ fun oda ... ni Akan. ... tutu nigbati ojo ... poju ni Igbi ... fun e ... Irrado, Ẹlẹdẹ ati Pepeiye. ... ki a ma riku ọmọde, ... ki a ma riku iyawo, ... adiẹ, ... ioye nla ẹran ... do tabi Ẹlẹdẹ.

Orisi-risi orisa ogun lo mbẹ. Ogun Alagbẹde ti o rọ ... ohun ti a fi mbọ ni, ..., Akukọ adiẹ ... ẹmu Ogun Ọlọdẹ ti ... ohun ... fi mbọ o ni, Ẹmu, iṣu sisun ati Akukọ adie. Ogun Ọlọdẹ eju omi, ohun ti a fi mbọ ni Ẹiyẹl..., ẹkuru, ati obi. Ogun Agbẹroko ẹmu ati obi ni a fi mbọ o. Ogun Onira tabi Ogun Ọṣọsi ohun ti a fi mbọ ọ Ẹgbọ Aja ti a tẹ lọda, tabi ẹlẹdẹ ti a tẹ lọda. Ogun Onigbajamọ, etutu rẹ obi, Irun ori Ẹmu, Epo ati iṣu sisun. Ṣugbọn Ogun kan tun mbẹ, ti o je alagba a bakanna, ... korun, iyawo ... ni Oronna, orisa yi lo ... ejo ja, tabi ki oyi kọ ... tabi ki ... di. Etutu rẹ ni Pepeiye, Egbo, ẹwa ati ... Sekete.

Olorisa ... gbodọ fi ... obẹ ... nigbati ... na ... lori ... ko ... yagbẹ si arin ọna ... ki o ... yagbẹ s ri igi, ko ... dalẹ, ko gbodọ ... elomiran.

Ọlọ ... ko gbodọ mu ẹmu, eyi ... ẹmu, yio ya ... bayi ni awọn Babalawo ... Orisala, Ọ ... Ọṣẹrẹ ... Ọgẹgẹ li ala, Alala kiniun, Ọba tapa-tapa lode Iranje. Anire' oiwa, Oniwa nire' Ọkọ arara lori pẹteki, Igbin are, oro, okọ Afin, Olowu la kẹ bi owu la, o'avigbo, ... ojo gbogbo bi bi odun. Olokobirikiti kalẹ lagun, Adebi adare, Opa... fi enyinju tanna, Atata ... eko.

Awọn Babalawo sọ fun wa pe Irumolẹ kan wa ti ... Jo ... eleri, nilu ... Ọ... a ... la ti bi, or kọ a ... Sadeju ọmọ ọba Oran ... iya rẹ ni Aladeju ... Olodumare ran iko si Aladejuwa wipe, yio bi ọmọ kan, ao ma pe e ni Jobi eleri. On lẹniti o kọkọ bere si sorọ nipa Ẹla Iwori. Ọba Alara ilu Ara lo pa Jobi eleri.

Orele ... opo, Afakalẹ gborọ. Awodi nla ọmọ Aforabata lọju Ọlọrun Bi a ba pe oku ni popo, ọmọ eaia ... ndahun, ara nyin ni ki ẹ ma pa, Iru Ẹkun.

# Isin mi Dun Lehin Ise



Sir JAMES ROBERTSON

Ni ọjọ Alamisi (Thursday) ọjọ kejidilogbọn oṣu June, 1956, ni Ọlọla Gomina agba Sir James Robertson wọ ọkọ Ofurufu ni dede agogo mẹji oru lo silu rẹ fun isinmi kuro l'ẹnu iṣẹ.

Ọlọla Sir Ralph Grey ni yio de'le de Gomina agba titi yio fi pada de.

Alọ a dara, abọ asunwọn o.

# Oba Obinrin Nilu Sweden



## Oba Elizabeth Keji

Alaiyelu a Ọba Obinrin lọ ... ilu Sweden wo awọn ... omi ti awọn ... se ... alarinrin fun u, ... pẹlu Bale rẹ Ọlọlajulọ oloye Duke of Edinburgh.

Ọkọ ... a npe Royal Yacht Britannia ni awọn ọlọla ... lọ silu Sweden.

... ọjọ ... pinmirin jojo.

## Oro ile wiwo d'ogun

EKO: Ọrọ ko ... ojo Thursday 28th ọjọ June 1956 nigbati awọn oyinbo ti o ... wo ile nilu Eko ... awọn ọlọpa de pẹlu kumo ... wọn, ti wọn si ... ti ... wo ile kan ni Portonovo Market street.

Awọn obinrin ... sopanpa wipe, b... yio ... ni yio ri, awọn ... ko ... wo, awọn ọlọpa fi le ... awọn obinrin fi le ọgbọn.

Awọn Ọlọpa so ... ni Broad Street ati ni Breadfruit Street Titi di bi ati okowo ... nṣe ni rogbodiyan ... yin, a ko si ti mọ ... ti yio bi. Gbogbo eniti o ... irohin na lo ... ri, gbogbo awọn obinrin Eko lo si funjá mọnu ... rẹ. Bi ọrọ na ba ti ... o tun ma gbọ.

## Agba-Emi-la Fun Ero Oko Ofurufu

Ọkunrin kan daba fun ijọba wipe ki awọn ma fun awọn ero inu ọkọ ofurufu ni agba-ẹmi-la kan ti a npe ni ede oyinbo bayi "Parachute".

Awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ paapa fi ara mọ ọrọ imọran rere yi. Nitoripe lasiko ogun ti o kọja lọ yi, gbogbo awọn ọmọ ogun ti a ba ko si inu ọkọ ofurufu lo nye nigbati jamba kan bade si ọkọ wọn.

Ẹ ṣakiyesi gbogbo awọn oyinbo ọlọkọ ori omi, gbogbo ẹniti o ba ti lọ si irin ti o kọja ilu Saro ni awọn o fun ni agba-mi-la kan ti a npe ni "Life Belt". Nwọn fun wọn bẹ ni ori ... jamba yio bade si ọkọ na lairotẹlẹ. A bẹ Ijọba ki o da ọrọ yi ro.

Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Koranko Street P. O. Box 457 Lagos Phone 23178